# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Akoje**

Enia ma jẹki t'enia sunwọn, t'eni ma sunwọn ko ni gbo. Apa omode ko e ka igi Ọṣe, yio ma doyika.

VOL. XIII No 692 LAGOS. SATURDAY JUNE 3, — JUNE 9, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# ATUNDA EJO ADELABU PENKELE MESI

EKO Lẹhin ọdun mẹta gbako ti awọn Ẹbi Ologbe Adelabu ati awọn ẹbi Ologbe Adegoke Arẹmu ti gba idajọ ni kotu nla ni Ibadan wipe ki ẹga ile iṣẹ Younan & Sons lọ san ẹgbẹrun mẹfa Pounun (£6000) fun wọn, ni a tun ẹjọ yi gbe dide ni Kotu nla ni Eko. Onidajọ Agba ni Eko da ejọ na ru, osi paṣẹ wipe Younan ma san Owini fun awọn ẹbi Adelabu nitoripe ẹjọ won ko mọyanlori pẹlu owo irin ẹsẹ.

## Gbanjare Omode Kan

EKO - Ọdọmọde kan, ọmọ ọdun mẹsan Abudu Latifu ni abule Makoko sọnu a si nwa, Abudu Latifu gato ẹsẹ mẹrin, aṣọ agbada ni o wọ jade. Atunpe ni Taiwo

## Owo Titun Wolu

EKO - Kobokobo titun ati Epini titun ni ijọba ti tu silẹ lati ile ifi-owopamọsi ti Ijọba ni ọjọ Alamisi ti o lọ yi Thursday June 1, 1961. Ogunlọgọ awọn enia ni wọn lọ ṣe owo titun yi.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telepone : London Wall 4303 — Cab'es & Telegrams Natbaniger London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## OBINRIN TO LO KO ISE ARANSO



Aworan ti a nwo yi niti akẹkọ obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Anna Mary Uzoka t'o lọ ko iṣẹ afabere ṣe ọna sara aṣọ ati awọn iṣe ile nilu Oyinbo.

## Jamba Moto Po Pupo Ni Odun yi

Ninu ọdun yi jamba moto pọ lọpọlọpọ, a si bẹ awọn awamoto lati ṣe suru gidigidi fun wiwa moto wọn. Paapa awọn Ọnikẹkẹ ni lati ṣe suru lọpọlọpọ, nitoripe ẹniti o ba ṣọ ara rẹ ni Ọlọrun nṣọ.

# OMOBA MARGARET NIBI AFI-HAN NILU OYINBO



Ọlọla nla Ọmọ'binrin Margaret ti a nwo ninu aworan yi nigbati o de ibi afihan awọn aworan eỌwọọya ti nwọn ṣe nilu Oyinbo laipẹ yi.

# FOLAMI SE ORIRE

EKO - Ọdọmọkunrin kan ti npe ni Fọlami tị ọgọlọrun jẹ mẹkanlelọgun ni o ṣe orire rinu ... ṣẹ yi. Nitori ... iṣe ... iwe-itan iṣe ni oṣu mẹta-mẹta Fọlami jẹ ọgbọn ... (Ẹgbẹrin mẹta).

## E Polowo Oja Yin Sinu Iwe Eleti - Ofe


## CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28 Balogun Street, Lagos


## E Mase Fi Omi Sofo




Ewo Aworan yi bi nwon ti yi ero omi tì kọroba kun akunya ti omi ndanu lasan. Eyi ko dara

## AGAN BE NILU SAPELE

SAPELE -- Enia meta lo wa nile Iwosan (Hospital) ilu Sapę'ę ninu awọn enia mọkanla ti ẹnikan gun lọbẹ.

A gbọ wipe ọkunrin agbẹ kan ki Kẹkẹ ologere (Bicycil) ti ẹlomiran mọlẹ, o si ngun lọ ni awọn enia ba nle lati mu, k'awi-k'afọ, o fa ọbẹ yọ, o si fi gun enia mọkanla, nwọn se itọju enia mẹjọ, nwọn si da enia meta duro sile Iwosan fun itọju Ọlọpa ti da enito gun wọn lọbẹ na duro fun iwadi.

Ni u Ilorin ni a tun gbọ wipe ẹnikan fi akufọ igo ge ara rẹ l'ọrun larin ode gbargba n i ọsan ọjọ kan ni u ọ'e tokọja, awọn enia ti o nlọ ti o mbọ diromọ lati gba ẹmi rẹ la, o si ba wọn wọ ijakadi, afi igbati oyi gbe ti o subu fun ọpọlọpọ ẹjẹ ti o 'i jade lara rẹ, iwọn to le gbe lọ si Ile Iwosan ( Hospital ) fun itọju.

Nwọn sọ wipe o ni alafia diẹdiẹ nisisiyi.

## OKU 'JA WOLU

NIGBATI OJ KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI SE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONISOWO LE ȘE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

## Gbogbo Ipinle Iwo-orun L'o Satilehin Fun Banki Ile Yoruba

IBADAN - O fẹrẹ kari gbogbo Igbimo ibilẹ ipinlẹ Iwo-orun ti nwon ti nṣe atilẹh'n fun Banki ilẹ Yoruba, (Nation Bank of Nigeria Ltd) lori iwadi ti Ijoba Apapọ pe le ti se lori iṣe Banki na.

Igbimọ ibile ilu Ayede.

de ti ṣe ipinnu lati fi owo igbimo bi £34,000 sinu Banki na bakanna ni Igbimọ ibile Iw'o-Udo-Esho ti pinnu lati da gbogbo owo wọn wa ninu Banki kan niiu Benin, sinu Banki na. Igbimọ ilu Benin paapa ti ṣe ipinnu bakanna.

Eyi fihan wipe gbogbo ipinlẹ Iwọ-orun l'o ni igbẹkẹle si Banki wọn.

## Nwon fi t'egbon t'aburo sun esun As'owo eru.

Makurdi—Awon ọkunrin meji ti nwọn jẹ t'ẹgbọn-t'aburo, Thomas Eze ati William Eze, ni nwọn mu wa siwaju adajọ ni Kotu Kekere ilu Makurdi ninu ọsẹ tokọja fun esun wibe nwọn ri iwe owo mọdaru lọwọ wọn ati pe nwọn ba nkan ti nwọn fẹ fi se afihan jẹ.

Awọn ọlọpa sọ wipe nibiti awọn ọd ran mejeji [illegible] wo mọdaru ni [illegible] ni agbegbe ilu Moma ni nwọn ka wọn mọ, ti nwọn si mu won.

Nwon koiti bere ọrọ lowo won, nwon g a id ro fun awọn mejeji lori adọta [illegible] kan [illegible] Odẹ won. Nwọn n [illegible] ọjọ na si oja keje oṣu June, 1961.

## Awon Mehaya Ta Ile Onile

EKO - Awọn Mehaya meji Buraimoh Raji ati Moses Olokundun ti nwọn haya ile No. 190, Ọpopo ọna Mọto Agege ni Mushin ni adajọ Kotu Asrisi ṣa wọn s'ẹwọn ọdun marun ati ọdun mẹta ni ọjọ Monday ọsẹ yi.

Awọn mejeji ni nwọn fi saa ẹsun wipe nwọn ta Ile onile fun Ezekiel Sebioba ni apo meta pọun ninu oṣu June ọdun tokọja.

Awọn mejeji ni adajọ ju sẹwọn fun iṣopampa jale, ifẹru gberu, ati iywe pada. Buraimoh Raji ọdun marun Moses Olokundun ọdun mẹta.

## OLOTU IJOBA MBA OMO AKEKO ILE NIGERIA S'AWADA



OLOTU ijọba ilu Oyinbo, Ọgbẹni Harold Macmillan ni o nba Dokita Newman Ọga olukọ ilewe ati awọn ọmọ akẹkọ ilẹ Nigeria meji Dokita Ezi-Ashi ati Dokita Laja lati ilu Ijẹbu-ode ṣ'awada lọhiati o ṣi ile ẹkọ ecogun Wolfson ti London ni Hammersmith laipe yi.

LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

# ELETI--OFE

ANJUWON KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street Lagos. "ELETI-OFE" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 672. SATURDAY JUNE 3, JUNE 9, 1961


# NATIONAL BANK, TIWA NI

Kosi orin ti a le kọ si ilu Gbedu afi ero ya wa woran. Ọrọ ti Banki eria dudu, an Banki kanşoşo na ti o je ti Yoruba ni ipinle Iwọ-orun ti Ijọba Apapọşe iẹ Nigeria paşe lati şe iwadi rẹ wo, dabi igbati enia ko ni alafisun ti a wipe ki o wa r'ọjọ.

Ejọ kini ẹ fẹ ki ẹnibẹ ro, tabi lori kini ohun ti yio ọjọ le lori ? I' ju tiwa, ọrọ na dabi afẹnil'ẹfẹ tabi eyit. awọn Yoruba ma npa l'owe pe : "Inunibini kokan a'mọ'wa hu", ibi mi şe be, "ojo gate, I ojo gate, o fi ẹse m ẹji ti o", ki enyin ọkawe wa fi oju inu wo aşẹ ti Ijọba Apapọşe wa pa yi.

Daju-daju, ọo ri wipe "kirikan mbẹ nisalẹ odo ti o nlu fun Iromi, n'itoripe Iromi ko jo lasan", ki ẹ maşe wipe owe wa şe npọ ninu ọrọ wa ọsẹ yi, atọna ni a fi awọn owe na se fun nyin.

Nisisiyi, nje ko ba han gedegbe fun enikeni lati mọ wipe awọn enia ipinle Iwọ-orun ile Nigeria ni ẹrikẹ'e si ile if wopamọsi wọn, (National Bank) ... gbogbo Ijẹbimo Ibile ni orişirişi ayika ilẹ ... ẹtẹruku ti Banki na pẹlu riiẹjo gbogbo owo ... Banki na.

Nj. National Bank tiwa ni işe.

# Do... ...damodi Tun Gba Kun Ewon Re

EKO - Andele Carapteli ti o ti şe ẹwọn ọdun mẹta ... mu wa si Kotu fun ẹsun ... erun bi Dokita atata, o si l'eru gb'owo. ... ẹsun yi ni o ti wọ ẹwọn ọdun mẹta ..., ẹjọ ... adẹlẹ ẹonun fun ni ..., ki o lọ şe ẹwọn ọdun meji ti o ba pe... ... o koko wọ.

# MORIAMO D'OLOGBE

EKO – Ni ọjọ Jimọ (Friday) ni ọsẹ ejọ kẹrindin-logbọn oşu May, ni iya ... Moriamo Majọrarani un Jalaisi, ti a ... işinku rẹ ... ni ilana ... Musulumi ni ọjọ Sunde, ọjọ kẹtadin-logbọn oşu May, 1961.

Mo pe ... ni ... ti awọn ẹbi, ọmọ ati ibatan iya ... yi ... nibi isinku rẹ, pataki ni ti ... rẹ ọkunrin Ogbẹni Sulaimon Majọrahun ti o nşawo bi ẹlẹdẹ, ... ti o şe bi ọmọlẹwabi fun iya rẹ ki ọlọjọ to de.

(Wo yoju loju ewe karun)

# Awon Olutoju Alaisan Pade Omoba



ỌJỌ kan pataki ni ọjọ ti awọn Olutọju Alaisan (Nurses) ni Ile Iwosan Poole, ni Dorset, pade Ọmọba Alexandra nigbati o duro be wọn sọrọ die ni atiko ti Ọmọba na lọ si Ile Alabiyamọ titun ni lati fi okuta ipilẹ lelẹ fun Ile Iwosan ti Poole titun mimu.

L'ọsan ọjọ na ni Ọmọba tun lọ bẹ Ibudo Şọja wo ni Lulworth, ti o lọ ri awọn ọm ogun ori ẹşin ti awọn fi oye Ọgagun nla (Colonel) da l'ọla le lori.


**Plushes, Velvet. Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street. (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## Moriamo D'ologbe

(O bere loju ewe kerin)

Alhaji Immam Jimo ti Mogaliji Idi-Oro ni o se eto isinku na pelu awon jonma Musulumi enia pataki-pataki nilu Eko ati lati ilu Abeokuta. A ki Ogbeni wa, Suberu Labitan ku agba, a si ki awon omo oloku Ogbeni Sulaimon Majenrahun, Iyafin Sariyu ati Taiwo ku inawo, nwon ku ateyinde Iya won. Ki Olorun fi omo rere gb'ehin enyin na.

## Abo Iwadi Ti Awon Alase Ijoba Wa Lo Se Ni FernandoPo.

EKO - Ninu ipade ti A'ase ijoba Apapose wa se pelu awon Oniwe Irohin, Ogbeni J. M. Johnson so ninu oro re wipe ise ti awon lo se nilu FernandoPo yori si rere. O so wipe owo awon osise omo ilu Nigeria yio di ilopo meji tabi jubelo lati ibere osu yi.

Ekun'wo ise won ra yio di porun merin sile meji ati kobo merin (£4 2s.4d) lososu dipo ponun kan sile metala ati kobo merin ti nwon ti ngba tele ri. Awon Olotu ise yio si ma yo pon-nu kan abo (£1.10s) si ipamo fun won dipo poun kan ti nwon ti nyo ri, nwon yio si ma san ponun meji sile mejila ati kobo merin (£2.12.4) fun won dipo sile metala ati kobo merin 13/4d ti nwon ti nsan fun won tele.



Owo ti nwon nyo si ipamo fun won na ni nwon yio san pada fun won nigbati awon ba pari adehun ise odun meji ti nwon se.

Ogbeni J. M. Johnson so wipe ayipada ti wa ninu ise awon omo ile Nigeria nilu FernandoPo, yato si igbati o lo, be won wo ninu odun 1957. O so wipe gbogbo adehun ti awon se lohun ni o yori si rere. Owo oko awon osise lo si ibi ise won yio di sile kan abo (1/6d) dipo Sisi (6d) ti nwon ti nfun won ri

Lehinti awon se akatakiti oro titi pelu awon Alase Paiyan (Spanish Authority) awon se adehun lori koko mesan wonyi:-

1. Awon Alabojuwo ise ijoba Nigeria yio ma lo be awon osise wo ninu oko ibiti nwon osise lai gbase ki nwon to se be. Lati le mas mo inira won.

2. Gbigba iwe ase ki enia to le kojá lati ibikan si ibikeji yio paro tabi ko ni si mo

3. Ile ti o dara fun awon osise lati ma gbe gegebi ti ile Nigeria.

4. Ki ijiya awon Lebira ti o ba se ese kekere ma se po mo.

5. Ki nwon maa se ejo awon ti o ba se Pelu Alabojuwo ise ijoba (Labour Officers.)

6. Ekun'wo fun siga ati owo oko sibi ise-sile kan abo dipo sisi tele ri

7. Sisan owo ina fun eniti o ba farapa lenu ise re.

8. Ni tulasi ni nwon fi nilati da awon ebi eniti o ba ku pada wa sile.

9. Iyawo awon osise ko gbodo pe meji ayafi okan soso lohun ki o ma ba si wahala.

## Omo Akeko Ilu Saro Fa Asia Ominira Soke Nilu Oyinbo



Ogbeni Rodney Williams, ti ise Akonije egbe awon omo akeko ti ilu Saro nilu Oyinbo, ni a nwo ninu aworan yi ti o n'e fa asia ominira ilu Saro s'oke nibi ayeye igb'ominira ilu Saro ni ojo keta-din-logbon osu April, nilu Oyinbo, ni oju'de Gbongan nla ti'u Leeds.

Awon omo ile Saro ti o duro pelu Rodney ni awon ti o nsise nilu Leeds.

## Oloye Obadeyi D'ologbe

Abeokuta— Ni ọjọ ose, (Sunday) ọjọ kejidinlọgbọn oṣu May, 1961 ni ẹhinti Oloye Jaa Obadeyi ṣe igbeyawo ko pelu, obinrin kan ti ... nṣise itọju alaisan nilu Abeokuta, ni ọlọjọ de si.

Gegebi a ti gbo irohin na si ni wipe lẹhin wa ati melọ ti Oloye i awo re Bisi Ọdesanya t i nwon npada lọ si ile iyawo oke Agowu, nigbati awon enia ti ... ti ṣe iyẹsi won, lehinti nwon ti o sibi ti oba t tun ... ade' ni won p de ... de ... iyawo re, ni ... ti ... fi d kn ... Obadeyi fi iyawo ... ti ... ọmọ metala ... s e ... nibi ... won em ... re wa nilu Oyinbo ti ... n nko ẹkọ.

Nwọn si ti gbe oku re ... s' Eko fun ayẹwo ki ... to lọ sin ni ọjọ Alamisi ... se yi. Ile re mbẹ ni Oba ... ba Street ni Ebute-metta.

## IPADE ISESE ENIA DUDU

(O bere ninu Iwe wa ọse to kọja)

Nitorina gbogbo awon Aju Ẹlẹsin Iṣẹse ti ẹ b a mọ ki ẹ wi fun wọn ki o wa ki ajijọ sowọpọ nis'siyi eto, ti ẹka Ila orun (Eastern Region) nlọ dede bẹ ni ti Ile Aruwa (Northern Region) ti ilẹ Yoruba ti fi idimulẹ ṣinṣin. Olodumare ati awọn Iṣẹse na ki o jẹ ki le ṣe Aṣeyọri. Aṣẹ.

Emi ọmọ Iya yin nitı Iṣẹṣe.
Oloye Fagbemi Ajanaku

Araba Eko.
Baba Ẹgbẹ

Lẹhin Ọrọ re yi, Olukuluku lati ọpọlọpọ ilu ti o sọ ọrọ nipa bi Aje awọn ti fi ara mọ e o Isowọpọ yi si. Ara a w ọ n si wa sọrọ nihin, Iya afin Abiodun Alagbe Onibuku (Ikorodu) Iya Afin Fawehinde Olori Olubalala, Iya Afin Anilẹ Balogun Iọṣun (Mushin) Ọmọ ... Falade Alagba Oje Eko, Ajenifuja Majeobaje (Iganmu ...) Ọrunmila (Akinboto Gbajigan) Oloye Kashinde Alapinni (Oje Remọ) Ọjẹlade Oje Ado Ekiti).

(Wo yoku Iojo e w e kẹje)

## Ikilo Lori Ekunmi Okun Alasia

EKO - Alaṣẹ o k o ilẹ ati ti Ofurufu ṣe ikilọ lori ẹkun'mi okun Alaṣia (Victoria Beach) ti o kun akunya lọsẹ to k ja, wipe ẹkun'mi na koiti duro, omi yio si ma kun siwaju ati siwaju fun bi ọjọ meji si.

Ẹkun omi okun na fyio ma ṣe ni deedee agogo marun owurọ si m ẹ f a, bakanna ni yio ma kun ni aṣalẹ ni asiko kanna.

Nitori bẹ, ki olukuluku enia ṣora nipa wiwẹ ninu okun fun ọjọ mẹwa Oju Opopo ọna ko si ni ... gba kọja ni awon asiko ti a daruko wonyi.

## IAMBA OKO OFURUFU

Singapore- Irohin kan wa wipe Ọkọ ofurufu kan ti o ko ero ... etala ni ... ti o si gb'ina nilu Singapore ni ọjọ Monday ose yi.

A ... wipe ... ni a ... enia kan l'aye ninu awọn ... metala ti o wa ninu Ok ... na.

S... mi ... Oluwa.

... a Iwe Irohin
... Eleti - Ofe

## Olotu Ijoba Ominira Ilu Saro Yio Be Ilu Oyinbo Wo



SIERRA LEONE — 'A gbọ pe nwọn ti fi iwe ipe ranṣẹ si Olotu ijọba ilu Saro, ọlọ a Sir Milton Margai ti o ngbọwọ lọwọ Akọwe ... ilu Oyinbo ti a nwo ninu aworan yi, wipe k i o wa sibi igbeyawo ọmọba Oloye nla Duke of Kent nilu York ni ọjọ kejọ oṣu June, 1961, yi.

Sir Milton Margai yio de silu London ni ọjọ kefa oṣu June 1961, fun ti igbeyawo na.

# EKO AWON OMODE.

Ile iwe fun ẹkọ ọmọ jẹ ohun ti o dara pupọ fun ilu Enia Dudu pataki ni Ilu Eko. Awọn Oniwasu lailai se wahala pupọ ki wọn to ri awọn ọmọ wẹwẹ diẹ ti awọn nkọ nigbana.

Awọn Imale k'on nfẹ lati gbo oro Şikuru si eti wọn, b ni wọn, ko f ... m ... ọn lọ si ile iwe, nitoripe o ... ko a ... ọn ọmọde ni ... lojudi l'olu wọn ati pe awọn ọmọ Kiriyọ ti nwọn nlọ i ile iwe ki i dabab, beni idọb l- ni ọmọ n'l ib ba wọn.

Wo Y ku Lọ Eko Kejo.

## ORO BABA O!!!

Obinrin ko gbẹdọ mọ Oro" nigbati kan ni Shagamu ni Ọgbẹni alatako sọ wipe ki adajọ jẹ ki awọn obinrin ti o wa ni kotu jade nitoripe on fẹ pe ẹlẹri kan ti yio fi han kotu gẹgẹbi awọn ti şa fi oro sede.

Awon enia mẹta n a mba se ejọ yi ni Kotu Ẹjọ yi koyiti pari

# ENIKAN PE JESU OYINGBO LEJO AGBERE

IBADAN - Pẹlu omi ni oju mẹjeji rẹ ni obinrin kan ti anpe orukọ rẹ ni Iyabọ Akinrinade fi duro siwaju apoti ni kotu nla ni Ibadan nigbati agbe ejọ re dide fun ẹsun wipe onşe agbere pẹlu ẹnikan ti o npe ararẹ ni Jesu.

Ọgbẹni Kay de ẹniti npe gẹgẹbi ẹlẹri si ọrọ yi sọ wipe ọmọ Ijọ ni on jẹ fun Ọgbẹni Odumosu (Jesu Oyingbo) on ni alarina larin Iyabọ ati Ogbeni Odumosu ran si baba Iyabọ, şugbọn Baba Iyabọ ko gba isẹ ti on jẹ. Ninu oşu November 1956 ni Iyabọ ko lo si ile Odumosu ni 40 Denton St. Ẹniti o tun jeri si Ọgbẹni Adekoya, sọ wipe on ri oyun ninu Iyabọ ni igbati wọn se ọmọ ẹgbẹ ijọ Odumosun on ma igbati obi ọmọ na, Ni igbana ni Baba Iyabọ kuro ninu Ijọ wọn ni ori wipe ko fi ara mọ awọn ohun wọyi. Ejọ na k... ẹzzi

# IPADE ISESE ENIA DUDU

(O tẹsiwaju lati oju ewe kẹta)

Ajitẹdun Kabba ati K bba ati ọpọlọpọ aşoju lati Ilu Okere ichin gbogbo ọrọ yi, Oluwo Joga Oke ti ijọ Ẹlẹsin Işẹ (Ọrunmila) Ilupesin gba ijọ na ni iyanju lati inu odu mimọ, Akoda Abimbọla Sava e si fi awure pari Ipade na.

Ipade na pinu lati şe Ipade ti oşu mẹta ti ombọ ni Ikor du, ti o u mẹfa ni M ta.

## Eunice Bloom Pelu Bale Obinirin Ilu Oyinbo



Ọmọ ọdun meje, Eunice Bloom lati ilẹ Nigeria ti a nwo ninu awọran yi, ti o nrerin muṣẹ si Balẹ obinrin Lady Waley Cohen, (Mayoress of the City of London) tilu nla London nigbati o nbe idi ẹdodo daradara kan fi ta Mayoress na lọrẹ.

Ọdọmọbinrin Eunice Bloom yi jẹ odi enia ti nwọn mu wa lati ilẹ Nigeria silu Oyinbo fun ẹkọ, eyiti nwọn se apejọ fun, ti alẹ obinrin (Mayoress) Ilu Oyinbo wa sibẹ v a şe ikede itọrọ ẹbun fun awọn odi.

Kia ... ase gbegbe pe odi enia ni Eunice ọmọ ọdun meje ...

## KA FI ORO RO ARA ENI WO

T he ... ema ... tun fu... ... iyipada iti ewe ... eyti o ma d ... ... eka kan gegebi idanwo, omi... ... de ba eni la... ti fib... pe gbekele eni ... n. Nigeri... pe bi ya o ti gbekele enikan gegebi omo iya tabi ore pataki tabi ore pataki tabi ebi pe ... bawu nigbati la-baja ba si wa ko si owu, nigbati aiye ba si wa lowo re tabi niwon igbati o ba ti eri je ti o ri mu ti omo araiye nba o je ti nwon bao mu o ko le mo iru ipo ti o wa, o di igbati adanwo aiye ba de ki o to mo ipo ti o wa.

Owe awon ba... a wa kan lo so bayi pe, ajeje ko dun bi enikan ko ba ni bi a ba ni la se ajeje. Egbon miran wa ti o je pe yio ma fe o niwon igbati o ba ti nrije ti o ... rimu, ore miran wa ti yio fe o pelu ohun gbogbo ti o ni yala ninu riri je tabi ninu airi je ninu ikedun ninu ironu Iponju ati wahala aiye eyi ti o je pe kosi eda ti o le wipe aipada aiye ko le de ba on nigbati olowo re ko gun igi ko ri ebia aiye Olorun ko fi ban enikan bi ebin ola yio di ri Iyoku di ose ti o mbo.

## Oba Mecca Nbo Wale Nigeria

KANO — Ni ojo ti o ti pe ni awon Musulumi jakejado ile Nigeria ati ni igun merin ile aiye ti lo si irin ajo lo si Mecca ati Medina, Sugbon ni odun yi ti awon Musulumi lo, agbo wipe Oba Mecca "King Saud" so wipe on parpa yio wa be ile Nigeria wo ni aipe yi.

Olotu Ijoba ile Hausa Sir, Ahmadu Bello ni omue lehin yi bo wale lati ilu Mecca.

Die ninu awon Bako Mecca ti o ti de ni Ahaji Ribadu ekan ninu awon olotu Ijoba apapo, Alhaji Zana Buker Dipcharima ati Alhaji Usman Sarkun.



HADJI RIBADU

Aworan oke yi niti Hadji Ribadu okan ninu awon Olotu Ijoba apapo ti o lo si Mecca ati Medina ni odun ni.

Hadji Ribadu wa ninu awon ti ilu yi lati Mecca.

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Losose Fun IDara Ya

## IŞIRO L'DE YORUBA

Gbogbo owo Yoruba bi a ti ka lati okan titi lo, beni a se nka owo oja gegebi oti wa ninu iwe yi. Chunkohun to ba de 20000 n sese gegebi o ti wa ninu iwe yi ohun... hun to ba de 20,000 ni ne eke ... ... oja titi ... ... hun mi... 1 Okan, 2Eji, 3 Eta, 4 Erin, 5 Arun, Efa,

(Iyoku di ose tombo)


# The New Fiat 600 D

### The Car You Dream To Own



767 C.C. ENGINE, 70 M.P.H.

Full four Seater with improved ventilation, Swirelling Draught deflectors and fully winding glass. Collapsible rear seat for more luggage room and optional front reclining seats. wew electro magnet starter and well proven full independent suspension on all four wheels.

**Price: £448 only**

Available at

**Leventis Motors Limited**

LAGOS (EB), IBADAN, KANO, JOS, KADUNA, PORT HARCOURT.
SUB-DISTRIBUTORS:
ARMEL'S TRANSPORT LIMITED
Benin-City, Onitsha & Aba.


## EKO AWON OMODE.

Nitoto Eria Dudu ni iteriba pupo, okan bi afojudi si jina si awon omo, re ni aiye atijo, eko iteriba yi ni nwon nfi ko gbogbo omo won, iba si dun pupo bo je pe awon Kiriyo ko mu asa awon Oyinbo sinu asa ilu won, ki gbogbo omo ba le ma se bakanna, boya ki ba ti buru to bi o ti buru to loni.

Awon omo Kiriyo ati awon omo Imale lailai mo owo ti o to lati fun obi ati asiwaju won ni ibikibi, awon Oluko won nsi nfi eyi ye won daradara, sugbon anu se wa ati si pe eyi ko ri be mo asa afojudi ti gbile l'arin awon omo Kiriyo ati omo Imale miran bakanna, o si wo won li ewu awo-kanle gege bi iyeri awon Momoyin Aguda la'lai. Afojudi po de'po gongo; won si nfi iwa buruku won ko ba obi won ni ... nigbati won ba bu iwa eyi ti a ni lati fi pe won ni "Abiko."

Ni ekoko lailai ofe ni gbogbo omo nko iwe ko si owo ibe, ebe pupo ni awon Oniwasu nma be awon obi ki won to le ma omo fun won lati ko ni iwe ati lati ma ri omo wewe ti yio le ma ba won kun orin ni S si ojo Isimi, Iwe ti nwon si nko awon nigbana ye koro tobe ti fi se opolopo won ni anfani ni igba aiye won.

IYOKU DI OSE TI MBO.

Printed & Published by The ... Printing and Publishing Company, ... P. O. Box ... Lagos ...